# Irinajo Mi Si Agbo Ile Ifẹlodun

Mo ki gbogbo ẹnyin onkawe Irohin-Imọlẹ, papa ẹnyin Ojulowo ọmọ ilẹ Igbomina, ẹ ku iṣẹ aje O.
Oluwa yio ma ṣe amọna gbogbo wa, Ajinde ara O ma jẹ O.

## Lati Ọwọ Ajẹgborodagba

Mo ro pe gbogbo nyin ni o ranti ibiti mo ba irohin irinajo mi de ni ọjọ jimọh to kọja, nipa bi awọn ẹbi Gbenle ti rawo nara ni ọjọ iwuye na tiwọn si fi ifẹ ododo ti nwọn ni si ara wọn han gẹgẹ bi Orukọ agbo-ile wọn.

### KARIMU GBENLE ṢE BẸRẸ

Mo ro pe irohin irinajo mi na ko ni kun to, bẹ si-ni ko ni dun to bi nko ba daruko diẹ ninu awọn ẹbi Gbenle pataki ti wọn nawo pelu awọn ọrẹ wọn ni ọjọ na, nitori nwọn ni bi ori kan ba sunwọn a kan igba ẹni.

Bi nko ba ni purọ tan ẹnyin Onkawe mi jẹ ọgbẹ-ni A. K. Karimu Ọlabamiji Gbenle ti ẹ nwo ninu aworan isale yi na wabi wọ si owo ni ọjọ na pelu awọn ọrẹ ati ojulumọ ti o je enia pataki larin ilu Eko ati kakiri ilẹ Naijiria ati oke-Okun ti nwọn wa sibi Iwu-ye na ni orukọ rẹ.

Ninu awọn enia pataki na ni Alhaji Lasisi Arowolo ti o wa lati ilu Isẹyin pẹlu awọn ọrẹ rẹ Alfa Arikeuṣọla, Alufa Ajijọla Inabi, ati Ọgbẹni Salawu Ajinde lati ilu Ọyọ ba-kanna ni Ọgbẹni Bọdu Taylor ti o jẹ ọkan ninu ogbokangi osiṣe 'Allied Newspaper' Eko ti owa sibi iwuye na.

Ninu awọn gbajumọ ati ojulowo ọmọ Igbomina ti o tun ba Ọgbẹni Karimu wa ni a ti ri awọn bi Ọgbẹni Lawal Adeoti, Yesufu Alabi, Yesufu Atolagbe. Asan Ibilowo Abudu Fọlorunṣọ, SalawuOtunọla, ati Ọgbẹni R. O Aroyẹhun.

Bakanna ni mo tun ri awọn orisirisi ẹgbẹ pelu aṣọ ẹgbẹjọda wọn ti o jẹ oju ni gbese ninu awọn ẹgbẹ ti owa ṣibẹ



Aworan oke yi ni ti Alagba, Olọla; Oloye Phillip Afọlayan Ajiboye Gbenle ati iyawo rẹ Iyaafin Barikisu Ajọkẹ Gbenle, eniti o wa ni owọ otun Oloye na ni Ọgbẹni Bello Gbenle ti Ọgbẹni Rapheal A Abikoye si wa lẹgbẹ osi.

ni ẹgbẹ Arowolo ti Ijọmu-Oro, ẹgbẹ awọn Jimoh ol ri ati bẹbẹ lo, Ọgbẹni Yesufu Olori ẹgbẹ Arowolo ṣe gudugudu meje ni ọjọ na nipa bi o ti nawo bi ẹlẹda. bẹsini awọn ọmọ ẹgbe lorişi-işi na wabi wọsi owo ni ọjọ na. Karimu Gbenle paapa fi Ọti ati onjẹ tẹ gbogbo awọn alabaşẹyẹ ọjọ na lọrun, emi Ajegboro dagba paapa jẹ onjẹ, mo si mu Ọti tit mo fi gbagbe Fila mi ati Şokoto mi silẹ ni ọjọ na.

Nigbati o di ẹwọ aşalẹ ti ọgbẹni Karimu ri bi gbogbo nkan ti ndun yungba, inu rẹ dun, on na si wọle lo, to wọ ẹwu ti o ba oju mu. ti o rẹ pe o jẹ oju ni gbeşe, bi o ti fe bọ sita ni awọn onilu ati Onirara ba bẹrẹsi nki ini on paapa wa bẹrẹ si awon bi ẹlẹda ti o si bọ si agbo on ati ọrẹ rẹ ọgbẹni Owolabi Aka bi pẹlu awọn iyawo Oloye ati awọn ọmọ jaiyejaiye ilu Eko ti o jẹ Ojulumọ ọgbẹni A. Karimu pẹlu aşọ ti o kọ bi mọnamọna oju orun ni wọn wa dẹru bẹrẹsi njo bi kokoro, ti nwọn si nawo bi Maleka ti o nşe owo ti gbogbo rẹ si ndun yungba.

Lẹhiu eyi ni awọn orişirişi ẹgbe na wa bọ si agbo ti nwọn si bẹrẹsi fi sẹ ra ijo pẹlu orin onilu pa u nọ elere Ejirẹ Igbaja, awọn ẹgbe bi Sumọnu Ayilara, Igbaja, Ẹgbẹ Juloti Agbọnda, ẹgbẹ Ala i Mulelọla. Oka - omini Oro.i ẹgbẹ Idirisu Omupo; ati awọn ẹgbẹ miran lati Ijomu- Oro ti aye ko si lati daruko sinu iwe yi.

Bi nko ba ni şe ete iọsọ, Ma sọ pe ọjọ nla ni ọjọ iwuye Alagba Phillip Gbenle yi jẹ fun gbogbo ọmọ Ijomu Oro ati Ekun mẹsan oro papa ilẹ Igbomina ni Apapọ

Emi Ajẹgborodagba lo anfani yi lati fi ki Oloye Gbenle ati awọn ẹbi rẹ, ku ina wo, nwọn si tun ku ifẹ ti nwọn ni si ara wọn gẹgẹbi oruko wọn fun

Wo oju ewe karun



Eniti ẹ nwo ninu aworan yi ti o joko ni Ogbẹni A K. Karimu Ọlabanji Gbenle ti o nşe olumọle wọde Oloye Phillip Afọlayan Gbenle ni ọjọ iwuye na on papa si na wabiwọsi owo ni ọjọ na. Ẹ ku inawo ọjọ o.

# ỌWẸ SI OLOTU

## Ibadan Wa Lẹhin Ẹgbẹ UPGA

Olotu Jọwọ gba mi ni aye diẹ lati fi ye awọn olori ẹgbẹ Dẹmọ to wa ni ilu Ibadan awọn enia bi Oloye Akinloye Olope Duro Ggundiran ati awọn Olori ẹgbẹ na bẹẹbẹ lọ lati lọ mọ daju pe awa ọmọ ilu Ibadan ati agbe gbe rẹ ko fi igba kan fi ẹgbẹ Afẹnifẹre ati Alakukọ silẹ.



Dọkita M. I. Okpara

Nitori eyi mo fẹ ki awọn ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ ati Olori egbẹ na lọ mọ daju pe ti ẹ ba ri ọwọ wa ti ẹ ko ri inu wa Dẹmọ sa lawa. Mo tun kan saara si Alhaji Obisẹsan fun ise ola to nse ni ilu Ibadan Oluwa na ko ni je ki ẹ se ti Amin nitori eyi awa ko si lẹhin ẹgbẹ Dẹmọ rara lọjọkejọ ẹgbẹ ilọsiwaju ni awa ọmọ ilu Ibadan ise a ko se ẹgbẹ ọdalẹ Olotu mo dupẹ fun aye ti ẹ gba mi.

Emi ni
Adesira Alata
Ibadan

ati agbe gbe rẹ pẹlu Olotu mo dupẹ lọwọ nyin ajinde yio ma ṣẹ o

Emi ni

Joseph Adeboyẹjọ
SHOMOLU

## Ẹgbẹ Afẹnifẹre Loni Ile Ifẹ

Inu mi yio dun bi Olotu ba le gba mi laye diẹ ninu iwe nyin oloyin mọmọ lati fi ye Oloye Rẹmi Fani Kayọde ti iṣe Igbakeji Olotu Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun ati ọkan ninu olori ẹgbẹ Dẹmọ Eleyi ni lati fi ye Oloye Fani-Kayọde pe awa ko gbe ilẹ wa ta fun ẹgbẹ N. P. C, idi eyi ni pe awọn ti mọ tẹlẹ pe ẹgbẹ Olomi N P. C. ko le se anfani kankan si Ipinlẹ Iwọ Orun paapa julọ ilu wa Ile-Ifẹ.



Oloye AWOLỌWỌ
Olori Ẹgbẹ Afẹnifẹre

Niotri eyi yio dara pupọ bi Oloye Fani Kayọde ba tete pada sinu ẹgbẹ Afẹnifẹre nitori inu ẹgbẹ na lo ti di ọmọ ẹgbẹ Alakukọ ati pe awọn ọmọ ẹgbẹ meji na ti papọ bayi yio si dara bi Oloye wa na ba tete pada sinu ẹgbẹ ọmọ Oduduwa ki o fi awọn ọdalẹ ẹgbẹ Dẹmọ silẹ Olotu. mo dupẹ aye ti ẹ gba mi.

Emi ni.

John Arẹmu
Ile-Ifẹ.

## Ṣhomolu Nfẹ Ijọju Ijọba

Olotu: Jọwọ gba mi ni aye diẹ ninu iwe nyin oloyinmọmọ lati kesi Ijọba ipinlẹ Iwọ Orun lati ṣe abẹwo si ilu Ṣhomolu ati Bariga lati mọ gẹgẹ bi ilu na ṣe ri ṣugbọn mo ro pe ti aba mu awọn ilu to ke pupọ ju ni Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria

Ṣugbọn kosi o un idagbasoke kankan to wa ni agbegbe na ọna ko dara ko si omi ẹrọ tabi ina elẹntiriki ni awọn adugbo bi ko ṣe pe ẹni to ba lowo ni yio gba sinu ilẹ wọn nitori eyi mo rọ Olotu Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria lati lo Ipo rẹ rere ki nwọn tete ṣe awọn nkan ti yio ba oju mu si ilu Shomolu


## Kini E Nduro Fun ?

Bi o ba ni asọ fun fifọ ati lilọ bi (wollen) asọ oke, Tapẹta Sapẹti ati orişirişi asọ ti o ba ni fun fifọ ati lilọ ni işẹju kan

TETE GBE WA SI ỌDỌ

**JOYCE LAUNDRETTE SERVICE**

34, Ojo — Oniyun Street,
Apapa Road Ebute Mẹta.

Kia ni ao ba ọ fọ ti o si ri gba ni ẹşẹ anna. A e wa gba ni ile rẹ, ki a si ko pada fun ọ ti a ba fọ tan kọ nomba ile rẹ ranşẹ si wa. Dan wa wo lẹkansoso ki o si ri bi işẹ wa dara tu Owo pọọku ni a si ngba.

## Aiye Toto African Healing Home

Bere ogun itaja Ti o daju Ti a şe ni Turari pẹlu lọfinda. Tete ra tirẹ ki o gbadun rẹ Irohin ko tc Afojuba orişirişi aruu ati ilọsiwaju Lẹnu işẹ pẹlu Ajẹbina ogun awọn Agba lo wa lọdọ wa

Office
7. Tadeyọ Road
Mushin

S. ỌLATUNDE
Native Doctor
6, Tadeyọ Rd
Mushin

BI ARA RẸ SILẸ PATAPATA LỌWỌ IKỌ BU BURU GBOGBO NIPA LILO EGBOGI:—

**RICHALET** dajitirọ. Işẹ rẹ lera k Kau fun Iwosan gbogo kokoro buburu i o bi

FUN ARUN ẸJẸ ninu, ẸJẸ ARA bi Mọnamọnra EIA GBOGBO




Meji rẹ ko si ni gbogbo awọn Egbogi ti nwọn npe ni TỌNIKI Ẹjẹ ti nwọn si nta Kakiri ni owo pọọku adi ọwọ tabi ki o lọ nilẹ ko di owo Iyẹn şe ewẹ, a wa ki ta awọn egbo i ba wọn yẹn rara tabi ti awọn npo ta ni ilẹ yi.

Gẹgẹbi awọn Onbiara wa ti mọ irufẹ awọn egbogi ba wọn yẹn a ma a ba ojulowo egbogi atata ti a ranşẹ fun tita lati awọn ilu Jamani Faranse ati awọn Tatambulu si Itali jẹ.

Mọ daju pe, bi ẹjẹ ara ko ba mọ daradara awọn amodiagbe ailera wọnyi le şe ọ Lakulaku orişirişi Inaru, Oju şuşu tabi didun, Jẹdijẹdi Ako ibu arun Ẹdọki, Aya didun pupọ ati Ekur laya.

Ara riro, lapalapa, Egbo-ẹsẹ modi Apo ile itọ, ẹyin didun tabi ibaradi riro pẹlu Egbogi RISALETI a ma a gbogbo kokoro buruku ti o wa ninu ẹjẹ rẹ patapata yio si fọ ẹjẹ mọ to nitoni pẹlu.

Şa dan igo rẹ kan wo iwọ yi si ma a rohin rẹ fun ẹlomiran pẹlu. PRICE 13/6d postage 36/

WATERLOO MEDICINE STORES
Palm church Street Lagos

# Ọmọ Igbomina Ẹ Fi Ibo Da Hassani L'are

## Lati Ọwọ Y. A. deyanju.

Mo fi iwe yi kesi gbogbo ọmọ Ẹgbẹ Afẹnifẹre Ilọrin Central Afọn Bala. Alapa, Onire, Akanbi Kara-Kara. Gbogbo awọn ọmọ Ẹgbẹ A G. ni adugbo kọkan ti o jẹ ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre. Mo fi tayọ tayọ gba nyin ni imọran wipe. Akoko ti awa yi ki a mura giri nipa ibo to mbọ wa yi paapa ọmọ bibi inu ilẹ ti mo da orukọ wọn. ninu iwe yi ki ẹmu ra silẹ ki a dibo fun Ọgbẹni Hassan Balogun.

Ọmọ nyin ni Hassan iṣe ati pe mo fẹ sọ fun nyin pe Hassani Balogun jẹ ọmọ kan ti o fi gbogbo ọjọ aiye rẹ ja fun ilọsiwaju ilẹ wa, Bi a ba dibo fun Hassani Balogun gbogbo nkan ti o nje wa ni iya ni Hassani Balogun yio ṣe fun wa ẹ dibo fun Hassani ọmọ nyin ni ise o. Pataki ohun ti omu nyin dibo fun Hassani ni wipe nigbati egbẹ Afẹnifere wa ni Igbimọ Ijọba ibile Afon, Bala, Alapa; Onire Akanbi karakara. gbogbo awọn ọna nyin ni nwọn tunṣe ti nwọn si gba awọn oṣiṣẹ ti nwọn si tunṣe di oni,

Nigbati Ẹgbẹ Afẹnifẹre wa ni Ijọba ibilẹ, awọn ni nwọn dopin ka ma mu ẹnia sin; bi Ẹru, awọn ni nwọn pin ki awọn Mo mu isu lọja ti anpe Aroja bi enia ba mu iṣu, Oka Baba, ere, Agbado. lọ s'ọja wọn Oyo nibe, Awọn ni nwọn pin pe ki ọmọde na owo ori ki a ma fun ni iwe ẹri awọn ni nwọn pin pe bi a ba da ina sun igi ninu oko nwọn a si jẹ ni iya pupọ

Nigbati ẹgbẹ Afẹnifere gba Ijọba ibilẹ ni owo N. P. C ni odun 1957 ni Ilọrin nigbana ni awọn ẹgbẹ Afẹnifẹre pin gbogbo nkan won yi. Ni asiko kan na ni Awọn Ọba ilẹ wa to ni owo Oṣu. ti ẹgbẹ Afẹnifẹre to gba akoso Ijọba ibilẹ na ko si pe eto wa fun awọn Ọba ati Ijoye awọn adugbo ti mo daruko rẹ nitori eyi ẹ dibo fun omọ ẹgbẹ Afẹnifẹre. Ṣugbọn mo ro pe ti ẹ ba lo wo asiko ti awọn ọmọ ẹgbe Olomi fi ona ẹre gba akoso Ijọba ibilẹ na ko si gbogbo eto miran ti awọn ṣe fun awọn Ọba wa ati pe owo oṣu ti awọn Ọba na ngba, nwọn ki iri gba lasiko.

Nitori na ti a ba dibo wa fun ọmọ ẹgbẹ Afenifẹre ọmọ nyin Hassan Balogun ki ẹ mọ pe ohun rere yio wa si ilẹ nyin lasiko Ijọba ẹgbẹ Afẹnifẹre Emi ni ero pe a ko gbodọ gbagbe ore ti ẹ bẹ Ol pẹ ṣe fun wa. Ọgbẹni Hassan Balogun lole yọ nyin kuro ninu wahala eyi to jẹ pe gbogbo nkan ti yio mu ilọsiwaju wa fun nyin ni yio ma de ọwọ nyin ẹ jẹ ki a sun ki a ronu wa ki a si dibo fun ẹgbẹ Afẹnifẹre.

Ẹnyin ọmọ ilu Ojoku nkan ti ẹ si mọ daju ni pe Ilu Baba ati Iya Hassan ni Ojoko iṣe nitori eyi ibo nyin lo la nkan rere wa si ile na.

Mo si fi eleyi ran nyin leti lati ja fun gegbi ẹgbẹ Afẹnifẹre yio'ṣe ie wọle ibo to mbọ yi Ki Ogbeni wa ọmọ wa Hassan Balogun si wọle ibo to mbọ yi o

Mo tun fẹ bẹrẹ lọwọ ẹgbẹ Olomi NPC ti ki nwọn sọ iru nkan rere ti nwọn ṣe si ilẹ wa lati igbati nwọn ti nṣe akoso Ijọba. Mo ro pe ti ẹnyin enia wa ba lo gbe oye wo iru nkan ti awọn ẹgbẹ Olomi nse fun wa lori gẹgẹbi nwọn ṣe na owo ka eyi ti nwọn sọ pe nwọn fi nṣe ọna lati Ikotun de Offa eyi ti owo pari ọna na (£30, 550 14/-8d) eyi to jẹ ibusọ mẹsan (9miles) si ilu Ọffa eyi ti o jẹ pe Ijọba NPC lo gba lọwọ wa. Nigbati ẹgbẹ Afẹnifẹre wa nṣe akoso Ijọba ibilẹ ni nwọn gba ẹgbẹ ajumọṣe na ti nwọn tuu kọ Post Offic ti owo rẹ jẹ (£2. 500 12/-3d sugbọn Ijọba ẹgbẹ Olomi NPC tun gba lọwọ wa. Njẹ ko yẹ ki a mọ iru ore ti ẹgbẹ Afẹnifẹre ṣe fun wa ki a si dibo fun ẹgbẹ na ki a kọ egbe Olomi NPC sile eyi ti ko wa ire kankan mọ ile wa.

Nitori eyi ẹnyin elegbe mi ẹ jẹ ki a dibo wa fun egbe Afenifere eyi to jẹ pe ọmọ wa Hassan Balogun a o le dibo wa fun. Ẹ dibo nyinn fun egbe ki e je a kọ amusu'imi NPC ti ko wa ire mọ awa enia ilu to wa loke iwe yi, o di owo nyin o, o di gba diẹ na.

---

LATI OJU EWE KEJI

agboile Oloye Oloye wa na ife darape ti a ba le ni ifẹ otitọ si ara wa, ko ba je larin ẹbi tabi larin ọrẹ, ni dun

Nitorina mo ro pe iru ifẹ ti awọn ẹbi Gbenle ni yio jẹ arikọgbọn ati lati jẹki awọn onkawe Irohin Imọlẹ mo riri ki enia ma gbe po pẹlu ifẹ otito ati idi ti awon Yoruba fi so di aṣa di oni oloni pe ifẹ dun pupo eyiti a yi si IFẸ LODUN

Ngo duro bayi loni bi o ba di otunlọ pẹlu ogo Oluwa ngo ma sọ bi Balẹ ilu Ojomu ṣe fi ọwọ si oye Olori ebi Gbenle ati iru ọrọ aponle ti o ko ranṣe si Oloye Phillip Gbenle ati ti fi ọwọ si.

---


## Gbanjo ! Gbanjo !!

FUN ỌDUN KERESIMESI

Eyi ni lati fi kede fun awọn onibara wa pe Ọja gbanjo wa bẹrẹ lati oni lọ titi di 30/12/64. Tete ra tirẹ ki o to kase nile

APEJUWE ILE ITA IWE WA

Wọ Boosi Mushin, sọkale ni Atẹ ọlara Bus Stop ! Bere ladipo Street, ti o ba rin titi Ladipọ, bere ILE IWE ODU - ABỌRE. Ti o ba de ibẹ tan, wa bere Nomba 5. Alaba Stiee Mushin, ile iṣẹ wa dojukọ ti 'ODUS SURF"

AWỌN ỌJA WA

Olubori Egbogi Ajẹbidan 40s di 30s Iwe Egbogi Ajẹbidan 25s di 22s Iwe Egbogi Awogba Aruu 20s di 17s Iwe Ilana Ifa purin tite ati etu sise 20s di 17 Iwe Afọṣẹ Isẹdalẹ Yoruba ati Psalmu Ajẹbidan 3 6 di 2s 6d Jurasi Isegun Aje 10s 6d di 8s Turari Itaja 10s di 6d 8s Turari Ala rere 10s 6d di 8s Iye owo Turari pangolo niti oke yi Turari ti o wa ninu pakẹti je 2s 6d pere Iwe Itumọ Ala Joseph Alala 5s Iwe Ariyan eto Irun o ti di 2s 6d Akọnni lẹsin pataki Islam 2s 6d Tailor's Measurement book di 1s 6d

Tenants Agreement Forms 10/6d di 5/ Gold Smith Forms
Certificate of Apprenticeship (mẹta) 17/6 di 10/6d

IỌJA TITUN TI A ṢẸṢẸ RI GBA

Abẹla mimọ fun adura tete Idamiloju (orişirişi awọ) pelu Turari.

| | |
|---|---|
| Abẹla mimọ fun itaja (Kowowọle pẹlu Turari | 20/- |
| „ „ „ Işegun Ajẹ pẹlu Turari | 20/- |

Lọfinda tabi Ororo ipara fun itaja, Işẹgun Ajẹ ati arisiki 30/- Igo kan

Fi owo ranşẹ tabi ki o wa ra ni ọdọ:—

J. O. Shoyinka
5. Alaba Street.
MUSHIN.

---

## Ipolowo Ọja Rẹ Ko Ti Ye

*Nitoripe*

O KO TI POLOWO ỌJA RẸ
SINU
**IROHIN IMỌLẸ**

T'ODUN KA FUN GBOGBO YORUBA

KỌWE IPOLOWO ỌJA RẸ SI
ADVRTISMENT MANAGER

**IROHIN IMỌLE**
16, Bamgbose Street Phone 21985

# IROHIN IMOLE

*IMOLE ORE AIYE, TENI GBOGBO LAWA*

NO 865 MONDAY DECEMBER 7, 1964 (2D


## Egbẹ UPGA Ṣo pe Awon Yio Ṣe eto Itoju Awon Omode

EKO:- Ninu Irohin kan to de owo wa lati owo ẹgbẹ ilọsiwaju ilẹ Naijiria UPGA ni awọn ọmọ ẹgbẹ na ti ṣe ileri pe ti ẹgbẹ wọn ba le gba ikoso Apapọ Ijọba ilẹ Naijiria lẹhin idibo si ile Igbimọ asofin ti apapọ Ijọba ilẹ Naijiria nwọn ni awọn yio ri pe ko ni si pe iyatọ kan wa larin awọn ọmọ ti obi ṣe lowo ati awọn ti Obi wọn ko si ni owo.

Awọn ọmọ ẹgbẹ ilọsiwaju ilẹ Naijiria tun ṣe alaye pe ẹgbẹ wọn yio si gbinyanju lati ri pe ko ni si pe iwa iyara ẹni sotọ wa ni arin awọn ọmọde ilẹ Naijiria ati pe Olukuluku awọn ọmọ na ni yio ni anfani lati ni ẹtọ bi ilọsiwaju ati idagbasoke yio ṣe wa larin gbogbo wọn patapata

Ẹgbẹ ilọsiwaju ilẹ Naijiria tun ṣe alaye pe gbogbo awọn ọmọde to wa ni ilẹ Najiria yio ni ẹto lati ni eto ẹkọ to daju ati pe gbogbo awọn ọmọ na ni yio si ni ẹto lati ṣe iṣẹ to ba wu Olukuluku ti nwọn ba jade ile ẹko wọn ti ẹgbẹ ilọsiwaju ilẹ Naijiria UPGA ba le gba akoso apapọ Ijọba ilẹ Naijiria lẹhin Idibo yi.

# AWỌN BABALAWO FẸ RAN ẸGBẸ UPGA LỌWỌ

## Nwọn Ni Awọn Wa Lẹhin Awolọwọ

**IJẸBU-ODE:- Nibi ipade ọjo meji kan ti awon ẹgbẹ Babalawo awon ẹgbe na ṣi a npe ni "Ijẹbu Oluwa 'odu to Falaṣe" ṣe ni ipari Ọṣe to koja ni Ijẹbu-Ode ni awon egbe Babalawo ni jakejado ekun Ijebu ti ṣe eto kan lehin ipade ti nwon fi ojo meji ṣe ti nwon si ni igbekele lori Oloye Ọbafemi Awolowlo Olori egbe Afenifẹre to wa logba Ẹwon bayi.**



**Oloye Obafẹmi Awolowo**
Olori Ẹgbẹ Afẹnifẹre

Oniwe Irohin wa to wa nibi ipade ti awọn Babalawo to wa ni ẹkun Ijẹbu ṣe si ṣe alaye ninu irohin rẹ pe awọn ẹgbẹ Babalawo na tun ṣe ileri ninu adehun ti nwọn ṣe pe awọn ni igbẹkẹ le pe awọn yio ri mo pe awọn wa ni isowọpo pẹlu ẹgbe ilọsiwaju ilẹ Naijiria UPGA ati lati ran wọn lọwọ eyi jẹ pe on ganan ni o le mu ireti wọn jẹ ayọ lati le jẹk Olori ẹgbẹ Afẹnifẹre to wa lọgba ẹwọn Oloye Awolọwọ eyiti jẹpe ti ẹgbẹ ilọsiwaju ilẹ Naijiria ba bori ibo lole mu Oloye Awolọwọ jade lọgba ẹwọn

Ninu ọrọ ti Olori awọn Babalawo fun gbogbo ẹkun Ijẹbu Ọgbẹni Ikudaisi Araba ni o ti ṣe alaye fun oniwe irohin wa nibi ipade na pe awọn si ti mọ daju pe laijẹ Oloye Awolọwọ kuro lọgba ẹwọn o ni eto aje ati ilọsiwaju ilẹ Naijiria ko lọ deede ti pe ko le si eto alafia ati ẹmi iṣọkan fun awon enia ilẹ Naijiria titi Oloye Awolọwọ yio fi jade kuro lọgba ẹwọn.

Ọgbeni Araba tun ṣe alaye pe [illegible]

bo da Oloye Awolọwọ silẹ ti awọn si fi si aye ipo to tọ si ti wa o ni igba na gan ni eto aje ilẹ Naijiria yio si ni ilọsiwaju ati pe ohun to jẹ pe awọn si ti ri daju ni pe gẹgẹbi yio ti ri ni yẹn titi Oloye Awolọwọ yio fi kuro lọgba ẹwọn ati pe nitori eyi o ni gbogbo awọn Babalawo to wa ni ẹkun Ijẹbu ni lati ri pe awọn faramọ ẹgbẹ ilọsiwaju ilẹ Naijiria UPGA ati pe lati ṣe iranlọwọ gẹgẹbi Oloye Awolọwọ yio se le jade.

Olori ẹgbẹ Babalawo ni ẹkun Ijẹbu na tun ṣe



D kita M. I Okpara
Olori Ẹgbẹ Alakukọ

alaye pe gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ Babalawo na ni ẹkun Ijẹbu lo si ti ṣe ileri pe awọn yio gbinyanju gẹgẹbi nwọn yio ṣe le ran

Wo Oju Ewe Kẹfa

## Ẹgbẹ Afẹnifẹre Gbe Ile Iṣẹ Wọn Lọ Si Ọṣhun

**IBADAN:— Ninu irohin kan to de owo wa lati owo igbakeji Akowe agba fun eto itankalẹ ẹgbẹ Afẹnifẹre Ọgbẹni J O Lawanson fi ye wa pe ẹgbẹ Afẹnifẹre ti gbe ile iṣẹ wọn lo si Oṣhogbo ni ẹkun Ọshun fun igba diẹ ki nwon to da olu ile iṣe egbe won pada si ilu Ibadan gegebi o ti ṣe wa tele.**

Ninu Irohin to jade lati ile iṣẹ ẹgbẹ Afẹnifẹre na ni nwọn ti ṣe alaye Ile Iṣẹ ẹgbẹ na ti nwọn gbe lọ si Ilu Oshogbo bayi ni Akọwe agba fun eto itankalẹ ẹgbẹ na Oloye S. T. Ọrẹdẹin yio si wa titi di asiko ti awọn yio fi da ile iṣẹ na pada si Ilu Ibadan lẹhin ti nwọn ba ṣe idibo si Ile Igbimọ Asofin ti Apapọ Ijọba Ilẹ Naijiria to mbọ yi.

Irohin tun fi ye wa pe gbogbo awọn iwe to jẹ pe nwọn kọ iwe si ile iṣẹ ẹgbẹ na ni Irohin na tun fi ye wa pe nwọn ni lati kọ awọn iwe na si Ile Iṣẹ wọn ni Ibadan gẹgẹbi o ti ṣe wa tẹlẹ ati pe ki nkan to fa ti iwe kikọ si Ile Iṣẹ na ni Oshogbo bi ko ṣe si Ile Iṣẹ ẹgbẹ na ni Ilu Ibadan.

Ninu ibẹrẹ ọdun yi ni ẹgbẹ Afẹnifẹre ko ile iṣẹ wọn lọ si Ilọba ni ẹkun Ọshun nigbati awọn ọmọ ẹgbẹ na ngbọ irohin labẹlẹ pe o ṣe iṣẹ ki wọn tu ile igbimọ aṣofin ti Ijọba Ipinlẹ Iwo Orun Naijiria ka nigbana ati paapa fun awọn idibo kan ti nwon ngbo pe nwọn fẹ ṣe si awọn aye ijoko ti o ṣ'ofo ni ile igbimo aṣofin ti Ijoba ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria.

Irohin si fi ye wa pe ile iṣẹ Afẹnifẹre ti nwon gbe lo si ilu Oshogbo na wa fun imura silẹ fun eto idibo si ile igbimo aṣofin ti apapo Ijoba ilẹ Naijiria to mbo yi lati le mọ gẹgẹbi awọn ẹgbẹ na yio ṣe, ṣe leri eto idibo na.